**10.** Dajudaju awọn ẹniti nwọn nnilara, awọn onigbagbọ ododo ọkunrin ati awọn onigbagbọ ododo obirin ti nwọn kò si ronupiwada, iyà ina Jahannama mbẹ fun wọn, iyà ina jonijoni si mbẹ fun wọn.

إِنَّ ٱلَّذِينَ فَتَنُوا۟ ٱلْمُؤْمِنِينَ وَٱلْمُؤْمِنَٰتِ ثُمَّ لَمْ يَتُوبُوا۟
فَلَهُمْ عَذَابُ جَهَنَّمَ وَلَهُمْ عَذَابُ ٱلْحَرِيقِ ﴿١٠﴾

**11.** Dajudaju awọn ẹniti o gbagbọ ni ododo ti nwọn si nṣe iṣẹ rere awọn ọgba idẹra wà fun wọn, ti awọn odo nṣan ni isalẹ̀ wọn. Iyẹn ni erenjẹ ti o tobi.

إِنَّ ٱلَّذِينَ ءَامَنُوا۟ وَعَمِلُوا۟ ٱلصَّٰلِحَٰتِ لَهُمْ جَنَّٰتٌ
تَجْرِى مِن تَحْتِهَا ٱلْأَنْهَٰرُ ذَٰلِكَ ٱلْفَوْزُ ٱلْكَبِيرُ ﴿١١﴾

**12.** Dajudaju ijẹniyà ti Oluwa rẹ le pupọ.

إِنَّ بَطْشَ رَبِّكَ لَشَدِيدٌ ﴿١٢﴾

**13.** Dajudaju On lo pilẹ̀ (da ẹda) On ni O ma tun u da.

إِنَّهُۥ هُوَ يُبْدِئُ وَيُعِيدُ ﴿١٣﴾

**14.** On na ni Alaforiji, Onifẹ.

وَهُوَ ٱلْغَفُورُ ٱلْوَدُودُ ﴿١٤﴾

**15.** On lo ni Itẹ-Ọla, Abọ̀wọ̀.

ذُو ٱلْعَرْشِ ٱلْمَجِيدُ ﴿١٥﴾

**16.** Aṣe-ohun ti o-wu U ni.

فَعَّالٌ لِّمَا يُرِيدُ ﴿١٦﴾

**17.** Njẹ iro awọn ọmọ-ogun ni ti wa ba Ọ bi?

هَلْ أَتَىٰكَ حَدِيثُ ٱلْجُنُودِ ﴿١٧﴾

**18.** ti Firiaona ati Samuda?

فِرْعَوْنَ وَثَمُودَ ﴿١٨﴾

**19.** Bẹẹkọ awọn alaigbagbọ wa ninu pipe ododo nirọ.

بَلِ ٱلَّذِينَ كَفَرُوا۟ فِى تَكْذِيبٍ ﴿١٩﴾

**20.** Bẹsini Ọlọhun ti ka wọn mọ (ni gbogbo àyè).

وَٱللَّهُ مِن وَرَآئِهِم مُّحِيطٌۢ ﴿٢٠﴾

**21.** Ṣugbọn on Al-Kurani jẹ titobi.

بَلْ هُوَ قُرْءَانٌ مَّجِيدٌ ﴿٢١﴾

**22.** Ninu wala ti a nṣọ.

فِى لَوْحٍ مَّحْفُوظٍۭ ﴿٢٢﴾

## *(86) Suratul - Tọ̃riki*

## سُورَةُ الطَّارِقِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi sanma bura ati awọn ohun ti o nde loru (Tọ̃riki).

وَٱلسَّمَآءِ وَٱلطَّارِقِ ١

**2.** Atipe kini yio fi mọ ọ kini ade loru nã jẹ?

وَمَآ أَدۡرَىٰكَ مَا ٱلطَّارِقُ ٢

**3.** Irawọ ti (imọlẹ rẹ̀) ntan roro ni.

ٱلنَّجۡمُ ٱلثَّاقِبُ ٣

**4.** Kòsi ẹmi kan ti o wà laijẹ pe ki oluṣọ kan wà lori rẹ̀ ti o nṣọ ọ.

إِن كُلُّ نَفۡسٖ لَّمَّا عَلَيۡهَا حَافِظٞ ٤

**5.** Nitorina ki enia woye si ohun ti a fi da a.

فَلۡيَنظُرِ ٱلۡإِنسَٰنُ مِمَّ خُلِقَ ٥

**6.** A da a lati inu omi ti o ntu jade.

خُلِقَ مِن مَّآءٖ دَافِقٖ ٦

**7.** O nyọ jade lati ãrin ibadi ati awọn egun igbaiya.

يَخۡرُجُ مِنۢ بَيۡنِ ٱلصُّلۡبِ وَٱلتَّرَآئِبِ ٧

**8.** Dajudaju On ni agbara lori didapada rẹ̀.

إِنَّهُۥ عَلَىٰ رَجۡعِهِۦ لَقَادِرٞ ٨

**9.** Ni ọjọ ti awọn aṣiri yio tu.

يَوۡمَ تُبۡلَى ٱلسَّرَآئِرُ ٩

**10.** Kò ni si agbara kan fun u kò si ni si alaranṣe kan.

فَمَا لَهُۥ مِن قُوَّةٖ وَلَا نَاصِرٖ ١٠

**11.** Mo fi sanma bura ti o ni ohun ti o ndẹhin walẹ.

وَٱلسَّمَآءِ ذَاتِ ٱلرَّجۡعِ ١١

**12.** Ati ilẹ̀ ti o nbu pẹ̀pẹ̀!

وَٱلۡأَرۡضِ ذَاتِ ٱلصَّدۡعِ ١٢

**13.** Dajudaju on (Al-Kurani) jẹ ọ̀rọ̀ kan ti o la alaye de opin.

إِنَّهُۥ لَقَوۡلٞ فَصۡلٞ ١٣

**14.** Atipe on ki işe ọ̀rọ̀ awadà.

وَمَا هُوَ بِالْهَزْلِ ﴿١٤﴾

**15.** Dajudaju nwọn nda ete lọna kan.

إِنَّهُمْ يَكِيدُونَ كَيْدًا ﴿١٥﴾

**16.** Emi nã si nwé-èwé lọna kan.

وَأَكِيدُ كَيْدًا ﴿١٦﴾

**17.** Nitorina dẹ awọn alaigbagbọ lẹkẹ ju wọn silẹ̀ fun igba diẹ.

فَمَهِّلِ الْكَافِرِينَ أَمْهِلْهُمْ رُوَيْدًا ﴿١٧﴾

## *(87) Suratul - A'alã*

سُورَةُ الأَعْلَى

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Şe afọmọ orukọ Oluwa rẹ ti O ga julọ (A'lã).

سَبِّحِ اسْمَ رَبِّكَ الْأَعْلَى ﴿١﴾

**2.** Ẹniti O da ẹda ti O şe (e) dọgbadọgba.

الَّذِي خَلَقَ فَسَوَّىٰ ﴿٢﴾

**3.** Atipe O pebubu (ẹda) O si fi mọna.

وَالَّذِي قَدَّرَ فَهَدَىٰ ﴿٣﴾

**4.** Atipe On ni Ẹniti O yọ koriko tutu jade.

وَالَّذِي أَخْرَجَ الْمَرْعَىٰ ﴿٤﴾

**5.** O si sọ (koriko na) di gbigbẹ ti o dudu.

فَجَعَلَهُ غُثَاءً أَحْوَىٰ ﴿٥﴾

**6.** Awa yio ke e fun ọ, ti irẹ kò fi ni gbagbe.

سَنُقْرِئُكَ فَلَا تَنسَىٰ ﴿٦﴾

**7.** Ayafi ohun ti Ọlọhun ba fẹ, dajudaju On ni O mọ ohun ti o han gbangba ati ohun ti o pamọ.

إِلَّا مَا شَاءَ اللَّهُ إِنَّهُ يَعْلَمُ الْجَهْرَ وَمَا يَخْفَىٰ ﴿٧﴾

**8.** A o si şe ni irọrun fun ọ ọna ti o rọrun (awọn isẹ rere).

وَنُيَسِّرُكَ لِلْيُسْرَىٰ ﴿٨﴾